IBADAN.
4/5/77
31 MAY 1977

WEEKS 43&44
Kongi WK 43
11 12 19
Wk 44
7 18 36
Asiko BK WK 43
31 38 39 43
Wk 44
3 15 25 37
Ross Wk 43
2 & 31
WK 44
22 & 49


# Imọlẹ Owurọ

ẸSIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!


SAMCO OF NIGERIA
WK 43
NAP 8 17 27
Perm 8 17 19 27 34
My Address ?
Not nessesary,
Always meet me in
Imole Owuro
Every Saturday
**4 12 32**

Independent Paper Vol. XV NO 798 SATURDAY MAY 21. – FRIDAY MAY 27, 1977 10K. (KOBO MEWA)

# 'BỌMBU OJUKWU' FẸ DA NKAN SILẸ

NṢE ni awọn akẹkọ ile ẹkọ giga kan sare aṣubulebu ni ipari ọsẹ ti o lọ yi nigba ti wọn kọ ebe titi nwọn fi kan "iku ṣi i pa ni" ninu ilẹ.

Ni ile iwe giga ti njẹ Obizi Community Secondary School, agbegbe Aboh Mbaise ni Ipinlẹ Imo ni iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ.

Irohin fi ye wa pe nigba ti awọn akẹkọ ile ẹkọ na lọ ṣiṣẹ oko, ti nwọn si bẹrẹ si i kọ ebe, ni nwọn ba kan ohun ọṣẹ oloro ti nwọn npe ni "bọmbu" ninu ilẹ.

Irohin fi kun un pe, lẹsẹkẹsẹ ni awọn ti o kọbe ri bọmbu ninu awọn akẹkọ na fi ariwo, "A ri bọmbu, a ri bọmbu" bọnu. Ni ọrọ ba di "B'o o lọ, ya fun mi" ninu oko na.

Ariwo awọn akẹkọ na ni awọn aladugbo gbọ ti o si da jinnijinni ati ipaiya silẹ.

Irohin sọ pe nigba ti o ṣe ni awọn Ọlọpa ti i maa da aporo lu bọmbu de ti nwọn si yege lati ba agbara bọmbu na jẹ.

Siwaju si i, irohin sọ pe, awọn Ọlọpa ti gbe bọmbu na lọ si olu ile iṣẹ wọn ni Eko fun ayẹwo.

Ninu ọrọ rẹ, agbọrọsọ awọn Ọlọpa fun Ipinlẹ Imo, Ọgbẹni D. W. Ojiagu, sọ fun awọn enia agbegbe na lati maṣe bẹru nitori ọrọ bọmbu na nitoripe awọn Ọlọpa ti ba gbogbo agbara rẹ jẹ.

Amoye kan sọ pe, o nilati jẹ pe awọn Ṣọja ọlọtẹ Ojukwu ni o ri i mọlẹ nibẹ ni akoko ogun abẹle ti o kọja ni ilẹ wa.

## Oruko Oba ti yio maa dade jade

IJỌBA Ologun Ipinlẹ Ọyọ, ti fi aṣẹ si i pe ki Ọba mẹtadinlaadọrin maa de ade onilẹkẹ ni Ipinlẹ na.



ỌBA GBADAMỌSI ADEBIMPE
Olubadan ti Ibadan.

Awọn Ọba alade na pọ si agbegbe Ọṣun ati ilẹ Ijẹṣa.

Pataki ninu awọn Ọba na ni Ọọni Ifẹ, Alaafin Ọyọ, Ọwa Obokun ilẹ Ijẹṣa, Olubadan Ibadan, Ọrangun ti Ile-Ila, Ṣọhun ti Ogbomọṣọ, Olugbọn, Arẹsa, Onikoyi, Ataọja Oṣogbo, Oluwo ati bẹẹ bẹẹ lọ.

Onirohin wa ran wa leti pe ara iṣẹ ti Ijọba Ologun ti o wa lori alefa bayi ni ilẹ Naijiria pinnu lati ṣe ni lati da ọla awọn Ọba pada fun wọn, lati yọwọ wọn kuro ninu iṣelu ati lati jẹ ki ipo wọn ni ọla.

(Woju ewe keji fun ẹkunrẹrẹ orukọ awọn Ọba mẹtadinlaadọrin na).


## Bosun Sowande (Omo Sobo Arobi Odu) Gbe Awo Jade



ALAGBA BỌSUN ṢOWANDE

OLOKIKI kan ninu alarofọ Ẹgba lori erọ Redio ati Telifiṣọn lati ọpọlọpọ ọdun: Alagba Bọsun Ṣowande (Ọṣọ Ṣọbọ Aro-bi-Odu Alaṣaro ọrọ) ti gbe awo agbayanu kan jade.

Ile Iṣẹ B M C RECORDS ni o gbe rẹkọọdu arofọ aladun rẹ titun na ti o kọ lorin ni ede Ẹgba jade fun igbadun gbogbo enia. Ni ana ni wọn bẹrẹ si i ta awo na.

Eyi ni awo akọkọ ti Alagba Ṣowande yio ṣe jade lati tẹ ifẹ awọn ọpọ enia ti o nke si i lati ṣe awo lọrun.

Akọle orin arofọ ti o wa ni oju awo na lọ bayi:

| OJU KINNI | OJU KEJI |
|---|---|
| Ẹsan | Fọgbọn Ọlọgbọn Ṣọgbọn |
| Ayọ | Ogun |
| | Itan Ọmọ Iya Mẹta |

Kaakiri gbogbo ile itaja rẹkọọdu ni ẹ ti le ri awo na ra tabi lọdọ
Olupinja (Distributor)
ANKERR SOUND,
86, Cemetery Street,
Ebute—Mẹta.

# ATIORO ỌMỌ ATIALA

## Itan Eko ati Omi (2)

LATI lailai,
Ara Eko
Ki i mu omi okun;
Okun lẹgbẹ ti iṣe
Olori omi-komi;
Nwọn ki i mu Ọsa,
Ti i ṣe Baalẹ Odo.
Nwọn ni,
Okun n'iyọ ninu,
Ọsa naa l'ẹgbin;
Atokun-atọsa,
Gbogbo wọn ko l'adun;
Idi niyi o
Gbogbo ẹnyin
Ti ngbọ wa
L'ori itan Eko
Ati omi,
Ti baba-nla ara Eko
Ki i fi i bu okun mu,
Ti baba wọn agba
Ki i fi bu ọsa wẹ;
Ti nwọn ki i buwẹ,
Ti nwọn ki i bu
Fi bọ ọmọ l'oju!




Ṣugbọn, iran baba wọn
L'o ni okun
Ti i ṣe Olori iru omi;
Iran baba Eko
L'o ni ọsa
Ti njọba iru ẹya Odo;
Nwọn a maa bọ Ọsa,
Nwọn a maa bọ
Omi okun pẹlu,
Nitori:
Nwọn sọ pe,
Gbogbo wọn pata
L'o nṣe l'oore;
Nwọn a tilẹ
Maa pitan nijọsi
L'aiye awọn
T'o bi baba iru wa
Pe, "kọkọrọ omi,
O nbẹ lọwọ Eleko".
Nwọn a ni:
"Ọjọ t'inu ba bi ilẹ
Ni i pa agbẹ;
Nwọn a ni
Ọjọ t'inu ba bi
Akọ ayunrẹ,
Ki i so l'ẹiyẹ jẹ;
Nwọn a ni,
Ọjọ t'inu ba bi igi
Ni i yalu omi;
Nwọn a ni,
Ọjọ t'inu ba bi omi
Ni i gbe igi lọ!
Nwọn a ni,
Ọjọ t'Eleko ba binu
T'o ba si kọkọrọ
Omi t'o nbẹ lọwọ rẹ,
Gbogbo Eko
Ni yio parẹ!
Nwọn a ni,
Ọjọ t'Eebo nlọ nilẹ yi
L'o fi kọkọrọ na fun
Ọba t'o jẹ
Ki Funfun too lọ!
Gẹgẹ bi nwọn ti nwi:
Ọlọrun Ọba Nikan
L'o le sọ nipa
Oniruuru ẹbọ
Ti nwọn ti ru si omi
Lati lailai wọn!
Nwọn bọ Ọsa titi
Ti baba nla wọn
Fi pada s'iwalẹ asa.
Nwọn ko mu Ọsa,
Nwọn ko bu
Omi okun bọju;
Ṣugbọn atokun-atọsa
Ni nfun wọn l'ẹja
Ti nwọn nta,
Ti nwọn nsejẹ:
Iyọ okun ko ja ẹja!
Ẹgbin odo ọsa ko run
L'ara ẹja ọsa;
Atẹja okun,
Atẹja ọsa
Gbogbo wọn dun lẹẹkẹ
O si nm'owo wale!
Oun ni
Baba nla wọn
Fi nbọ iwin omi;
Nitori, nwọn gbagbọ
Pe, iwin l'o ṣewere
T'o nṣe wọn l'oore.
O wa ya l'ode oni;
Omi mimu ko si,
Bi ti i ri l'ẹẹkọọkan
L'aiye awọn baba wọn;
Ojo ko rọ,
Omi Iju ko pọ;
Ijo ko to
Ara Aawẹ i jo,
Nibo ni
Ara Akinmọọrin
Yio woran?
Ara Iju ko r'omi to,
Taa ni i jara Eko isalẹ?
L'o ba wa di pe,
Omi okun
Ti a ti tẹnbẹlu
Pe, ko ṣe e mu l'omi
T'awọn agba ibẹrẹ
Ki i mu debi
Pe, nwọn yio bu sebẹ;
Omi oniyọ ọhun
L'o wa d'ẹhin yi
T'o di mọgaji ọfun:
Okun ni,
Nwọn nbu mu,
Okun ni,
Nwọn nbu wẹ,
Okun ni
Nwọn nbu bọju
Ti nwọn fi ndana!
Ọpẹlọpẹ Ijọba ilu
Ti ko jẹ ki
Omi ọhun ṣ'ẹṣe
Fun gbogbo wọn
Awọn l'o nbu oogun lu u
K'o ma ba a fa ọran.
Ko to di pe
Omi iyọ kọ wa mọ,
Oju wọn ri mọbo.
O da mi l'oju
P'ara Eko
Ko ni i gbagbe bọrọ.
ỌLỌLA ATIORO

# Ijoba gbe oruko Oba Alade Ipinle Oyo jade

IJỌBA Ipinlẹ Ọyọ ti gbe orukọ Ọba ti o lẹtọ lati maa de ade onilẹkẹ jade ni Ipinlẹ na. Ninu ọsẹ ti o kọja ni Ijọba fi ọwọ si i ki nwọn to kede rẹ fun aiye gbọ.

Mẹtadinlaadọrin (67) ni iye ọba na ni: Ooni Ifẹ, Alaafin Ọyọ, Olubadan Ibadan, Ọwa Obokun Ilẹ Ijẹṣa, Ọrangun Ila, Eleruwa Eruwa Ọwa - Oye Imẹsi—Ile, Akinla Ẹrin–Ijẹṣa, Ọwa Omiran Ẹsa–Oke, Ọlọtan Ọtan–Ile, Alare Ilare, Ado-Oko ti Idoko, Ajarẹgbẹ Ijaẹrẹgbẹ, Alada Ada–Owode, Ọmọmọ ti Ọmọ.

Ara won tun ni: Olufẹwara Ifẹwara, Olowu Owu-Ẹpẹ, Olusẹ Iṣẹ-Ijẹṣa, Ataọja Oṣogbo Olufọn Ifọn-Ọṣun, Ẹlẹrin Ẹrin, Ọlọba-Ile Ọba–Ile, Alawo Awo, Alara Ara, Ọlọjọ Ọjọ, Ọba Ido Ido Ọṣun, Olukọtun Ikọtun Olokuku Okuku, Akọọsin Eekọọsin, Oloyan Ọyan, Onigbaye Igbaye,

Ara wọn tun ni: Aragbiji Iragbiji, Ọwa Igbajọ, Ọlojarẹsi Irẹsi, Elende Eko-Ende, Ọlọna Ada, Ọlọbaagun Ọbagun, Ọlọrọruwọ Ọrọruwọ, Onirun Oke–Irun, Olore Ore, Eburu Ibı,

Ara wọn tun ni: Owa Ọtan–Aiyegbaju, Ọrangun Oke–Ila, Asaoni Ọra, Edigbọn Ẹdẹ, Arẹsadu Irẹsadu, Arẹsapa Irẹsapa, Onpetu Ijẹru, Alaasoko Isoko Ogbomọṣọ, Olugbọn Igbọn Ogbomọṣọ, Elejigbo Ejigbo, Alaasoko Isoko Ejigbo, Adimula Ifẹ – Ọdan, Ologburo Ogburo, Olowu Owu Ejigbo, Alato Ato, Alaye Aye, Oluka Ika, Oluwo Iwo, Akire Ikire.

Awọn yoku ni: Olowu Orile–Owu, Onisanbo, Ọgbọọro, Onitede Tede Ṣọhun Ogbomọṣọ, Onikoyi Ikoyi ati Onidere Idere.

Iwe ikede Ijọba na, eyi ti Akọwe Agba fun Ijọba Ipinlẹ Ọyọ Ọgbeni T. A. Akinyẹle kọwọbọ, sọ pe, lati ọjọ kinni oṣu kejila ọdun ti o kọja ni ılowosi Ijoba na ti bẹrẹ si i ṣiṣẹ.



ỌBA ADEYẸMI
Alaafin Ọyọ



ỌBA FAMỌDUN
Ọwa Igbajọ

# 15
# 47

## Akiyesi fun Onkawe

EYI ni lati kede fun gbogbo onkawe ti o ba nkowe "Ẹ GBỌ TEMI" si wa fun titẹjade, pe, ẹ gbodo maa kọ orukọ nyin ati ti Adirẹsi nyin tooto si ara iwe na.

Nitori pe, opolopo iwe ni a nri gba lati odo onkawe ti awon ti o ko won ko fi Adirẹsi won tooto si i l'ara.

Bakanna ni ẹlomiran yio kowe si wa lati ilu Eko, ṣugbon ti yio fi Adirẹsi awuruju si i pe lati "Bukuru" tabi "Ogbomoṣo" ni oun ti ko o.

Iru iwa yi poju lowo awon ti nkowe si wa, eyi ti o lodi si ilana iṣẹ wa.

A fe ki o ye olukuluku pe bi o ti wu ki oro inu iwe ti ẹ ko le to, a o fi tayotayo gba a yẹwo, a o si tẹ ẹ jade bi o ba yẹ, koda bi o jẹ pe awa paapaa ni oro na ba wi.

Nitorina bi a ba ri iwe kan gba ti ko tẹle ilana iṣẹ wa tabi ti ko ba mu ogbon dani; tabi ti ko ba le ṣanfani fun onkawe tabi ti oro inu rẹ ba lodi si ofin, a ko ni i tẹ ẹ jade

—OLOOTU

# Akédé ọ̀nà Iyè

ONAKANSOSO SI IYE AINIPEKUN

# Olotito ntan lo ninu awon omo enia (3)



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

"Ẹ ma si ba aileso iṣẹ okunkun kẹgbẹ pọ, ṣugbọn ẹ kuku maa ba wọn wi, nitori itiju tilẹ ni lati maa sọrọ nkan wọnni ti nwọn nṣe ni ikọkọ, ṣugbọn ohun gbogbo ti a nba wi ni imọlẹ i fi han. Nitori ohunkohun ti o ba fi nkan han, Imọlẹ ni". Efesu 5; 11-13.

Ọsẹ kẹta niyi ti a ti nṣe iwaasu l'abẹ akọle ti a kọ si oke iwe yi pe, "Olotitọ ntan lọ ninu awọn ọmọ enia". Ọdodo ni ọrọ na gẹgẹ bi iwọ ati emi ti le ri i l'ode oni.

A ti sọ iru awọn enia ti o gba ile aiye yi kan: Awọn oṣo, ajẹ, oloogun ika, ole, igara, alaiṣootọ, ọta ododo ọrọ Ọlọrun, ọta ojiṣẹ Ọlọrun tootọ, si pọ pupọ ninu ọmọ enia.

Ṣugbon Ọlọrun ko ni i ṣalai da awọn enia buburu aiye wọnyi l'ẹjọ bi nwọn ko ba ronupiwada.

Nitorina iwọ ọmọ enia: yala bi o jẹ pe iru awọn enia buburu ti a wi wọnyi nda ọ laamu, tabi bi o si jẹ pe iwọ paapaa jẹ ọkan ninu iru wọn, o san fun ọ ki o tete sa tọ Jesu Kristi lọ ripa titẹle ilana ti O fi silẹ fun iwọ ati emi lati tẹle ilana na nitori O ti sọ pe ẹnikẹni ti o ba gba Oun gbọ, ti gba Baba wa ti nbẹ ni ọrun gbọ niyẹn.

Mo si fẹ ki o ye o iwọ ọmọ enia pe, iru wahala yowu ki o le maa ṣe ninu aiye, ani, iru itara ti o wu ki o le ni si isin Ọlọrun, bi ki i ba ṣe nipasẹ Jesu Kristi, ani gẹgẹ bi Kristi ti nfẹ, asan ati imulẹmofo ni wahala ati itara rẹ ninu aiye yio jasi.

Njẹ nigba ti enia ba wa si aiye yi, ti o ni itara, ti o ṣe wahala, ṣugbọn ti gbogbo rẹ jasi asan, ere kini o jẹ fun iru ẹni bẹẹ? Kini anfani wiwa sinu aiye rẹ? Idi niyi ti o fi nilati ronu, iwọ ọmọ enia.

Ma ṣe jẹ ki ọrọ iwaasu yi koro leti rẹ nitoripe Ọrọ Ọlọrun dabi ina ti o njo ni, ṣugbọn iwọ ni ki o tete ṣe atunṣe iwa rẹ nibi ti o ba ku si.

Hẹrọdu Ọba ti o jẹ ọta ododo, ati Kaiafa Olori Alufaa ṣe aṣedanu l'aiye nitori nwọn doju ija kọ ododo nipa kikorira Jesu Kristi.

Bakanna ni o jẹ pe bi o ti wu ki enia kan jẹ ẹnirere tabi jẹ olusin to, ṣugbọn ti o ba korira Jesu Kristi, asan ati aṣedanu ni wahala iru ẹni bẹẹ ninu aiye yio jasi pẹlu. Nitorina, jẹ ki eyi jẹ mimọ fun ọ lati oni lọ.

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

Iwọ maṣe fi ara we Hẹrọdu, Kaiafa ati Judasi, awọn ti nwọn ṣe ọta ododo ti orukọ wọn si bajẹ ninu aiye ati niwaju Olodumare.

Awọn enia na l'o dabi oṣo, ajẹ alaiṣootọ, ati ẹmi buburu gbogbo ti o kun inu aiye l'oni; awọn ẹni ti ko bẹru Ọlọrun ti ko si pa ofin Rẹ mọ; awọn na ni a nkẹ si ọ l'oni lati maṣe fi ara we.

Iwọ ti o nṣe buburu ni ikọkọ ti o nsọ fun araiye pe rere ni o nṣe, Oluwa nwo ọ. "Oluwa wi pe, Emi o si sunmọ nyin fun idajọ, Emi o si ṣe ẹlẹri yiyara si awọn oṣo": Malaki 3;5.

Bibeli wi, pe, "Ọjọ na nbọ ti yio maa jo bi ina ileru ati gbogbo awọn agberaga ati gbogbo awọn oluṣe buburu yio da bi akeku koriko, ọjọ ti nbọ yio si jo wọn run, li Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, ti ki yio fi ku gbongbo tabi ẹka fun wọn" Malaki 4; 1.

Ohun pataki ti yio tilẹ mu awọn oṣo, ajẹ ati enia buburu gbogbo jẹbi ni pe, olootọ enia ni ọta wọn, Oluwa si ti ri i pe nwọn ṣoro mu fun Ọlọpa aiye toripe bi ẹnikan tilẹ mọ pe ajẹ ile oun nda ọmọ oun laamu ti o si tori bẹẹ fi ẹjọ sun Ọlọpa, niwọn igba ti Ọlọpa ko ba ti ka ada mọ iru ẹni bẹẹ lọwọ pe o fi pa enia tabi fi ri nkan ti iru ẹni bẹẹ fi lu enia pa, Ọlọpa ko ni i le mu un; ẹni ti a fi ẹsun kan si le pẹhinda ki o pe onitọhun l'ẹjọ ibanilorukọjẹ.

Ṣugbọn mo fẹ ki oye ọta ododo, ani mo fẹ ki o ye olukuluku enia pe, Oluwa ti o mọ iwa ikọkọ ati ti gbangba gbogbo enia sọ pe; Oun yio kọju ija si oṣo, Oun Oluwa yio pa gbogbo oluṣebuburu run pata. Oluwa ni Oun yio jo wọn run, nwọn yio si dabi akeku koriko.

Nitorina iwọ ọmọ enia ranti gbogbo iwaasu ti a ti nṣe l'ori ọrọ yi; tete ronu rẹ l'oni ki o si sakuro ni ikawọ eṣu atanni ati lọdọ awọn agalamọṣa, ki o si maa tọ Jesu Kristi lẹhin, iwọ yio si ṣe rere.

ADURA

Oluwa, fa mi kuro ninu iparun eṣu ki emi ma baa da bi ẹranko ati bi ohun ti ko wulo, nitori Jesu Kristi Oluwa wa, Aamin.

NIGERIA NEW STATES CO.

Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lo, Ile Iṣẹ wa wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.

IWE ỌRỌ ỌLỌRUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkookan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa, Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.

ADIRẸSI OLOOTU

OLOOTU,
IMOLE OWURO,
P.M.B. 5230,
IBADAN.

# Ẹ gbọ t'emi

## Eto Haji na dara

OLOOTU,

MO ka a ninu Imọlẹ Owurọ pe Ijọba ti fi ofin de arugbo, aboyun ati ọmọ ti ko ba ti i to ẹni ọdun mejila pe nwọn ko gbọdọ lọ si Haji. Bakanna ni Ijọba so pe, eniruuru eto ti nlọ lọwọ yio mu ki iṣoro ti arinrinajo maa ndojukọ ni Haji de opin.

Inu emi gẹgẹ bi ẹnikẹni dun si ofin na ati eto na ti Ijọba nṣe.

Bakanna ni mo tun gbọ pe Olori Ijọba wa, Ọgagun Agba Oluṣẹgun Ọbasanjo ti pe awon aṣaaju ẹsin Islam si ile iṣẹ rẹ nilu Eko, nibi ti o ti ṣalaye eto titun ti Ijọba na fẹ gbejade fun won.

Mo gbo pẹlu pe tayotayo ni nwon fi gba eto na wole ti nwon si dupẹ lowo Olori Ijoba na fun aniyan rẹ lati mu ki irorun ba awon ero Haji ati lati mu ki opin de ·i awon omo Naijiria ti nwon ntan si ilẹ Larubawa.

Gbogbo eyi l'o dara a si rọ Ijoba lati mu gbogbo eto ti nwon kede na ṣẹ ki irinajo Haji ba le rorun fun ẹnikẹni ti o ba fẹ rin in.

Emi ni,
Tiamiyu Ocilonise,
Eko.

## E diyele ounje na

OLOOTU,

MO ka a ninu Imolẹ Owuro laipẹ yi pe, "awon kan ti nwọn pe ni 'Eegun ilu' ni o wa nidi iṣẹlẹ na". Ki l'o ṣe ti ẹ ko daruko iru awon enia na fun wa?

Ibeere keji ni pe, bawo l'o ṣe jẹ pe awon Adiyeloja dojuko oti Bia nikan ni didiyele lai dojuko ounjẹ na? Tabi oti ni o ṣanfani ju ounjẹ lo ni?

Emi ni,
Sunday Akanbi,
Oṣodi—Eko.

Akiyesi

Ọrẹ wa Sunday, Idahun l'ori ibeere akoko ni pe, awon Ọlopa nikan l'o lẹtọ lati daruko enia kan ti oran dida ba kan. Bi awon Ọlopa ko ba ti i daruko rẹ, ẹnikẹni ko lẹto lati daruko. Ohun ti iwe irohin le ṣe na ni ki o ṣapejuwe iru ẹni bẹẹ, ki o si ṣalaye pe, awon Ọlopa ko ti i daruko rẹ nitori aabo ilu.

Idahun keji ni pe, o ṣoro fun Igbimo Adiyeloja lati diyele ounjẹ ti a nmu ninu oko ni ilẹ wa nitoripe ko si odiwon fun un, bẹẹ ni iru iwon ti a nlo ki i ṣe ti otito. Eleyi ṣoro gidigidi fun Igbimo Adiyeloja lati ṣe.

—OLOOTU

## Mo ki Akede Ona Iye

OLOOTU,

GBA mi l'aye lati kan saara si Akede Ọna Iye, Woli S. I. Owoọyẹ fun iwaasu manigbagbe ti o maa nṣe fun wa ninu Imọlẹ Owurọ nipa ti ọna Igbagbọ.

Mo tilẹ gbadun iwaasu rẹ ti akọle rẹ jẹ "A o rẹ Agberaga silẹ" ninu eyi ti o sọ itan kan fun wa.

Itan na kọ enia ni ọgbọn pupọ, mo si kan saara ki Woli wa na pe o ku iṣẹ. Iwaju ni ọpa ẹbiti rẹ yio maa re si; ki Jesu tubọ maa fi imọ kun imọ rẹ, Aamin.

Emi ni,
Ọlaniyi Adewara
Esiẹ.

FOR ALL YOUR

Electronics

Fans, Cookers, Radio sets, T .V.& Colour T.V. sets, coolers etc: at resonable prices

PATRONIZE

Aiyedetisola

Commercial

Electrical

Store:

N27 I.C.C STALL
AGODI GATE
IBADAN

# ISỌRỌ-N'IGBESI...

# IPADE (56)

A o ranti pe ni ọsẹ ti o kọja ni awọn Akewi wa Lawuyi Ogunniran ati Adeyẹmọ Ọjẹrinde bẹrẹ si i lọ ọrọ mọ ara wọn lọwọ l'ori "Oṣo, ajẹ ati oloogun ika". Adeyẹmọ Ọjẹrinde nfẹ ki Lawuyi Ogunniran sọ fun oun bi awọn nkan na ba nbẹ ṣugbọn Lawuyi Ogunniran nfẹ ki Adeyẹmọ sọ idi ti o fi wa beere iru ọrọ bẹẹ lọwọ oun nigba ti ouo ki i ṣe agbọrọsọ fun wọn.

Eyi mu ki Adeyẹmọ Ọjẹrinde bẹrẹ si i tọka si i fun Lawuyi pe, ṣe o fẹ sọ fun oun pe ko mọ nipa nkan na ni paapaa bi o ṣe jẹ pe arugbo kun inu ile wọn ati bẹẹbẹẹ lọ.

Ki a ma wulẹ sọrọ lọ bi ilẹ bi ẹni mọ, irohin Ipade t'ọsẹ yi lọ bayi:

Adeyẹmọ Ọjẹrinde

Ayinde ọmọ Ejigbọjọ,
Aroye ọrọ ko si l'oni
Jẹ k'a maa ba faaji bọ.
Ṣe o ranti pe,
Mo ni ki o sọ fun mi
B'oṣo nbẹ, b'ajẹ nbẹ,
Bi a si ni oloogun ika
Nitori, alakọwe ni nsọ pe,
Ko si 'hun t'o jọ bẹẹ rara,
Mo si fẹ ki o sọ 'di okodoro,
Bi o ko ba si le ṣalaye,
Jẹ k'a yara gbọ labare.

Lawuyi Ogunniran

Ṣe bi o ti sọ l'ọsẹ t'o kọja
Pe, ko si agbo ile
Ti ko si oṣo, ti ko si ajẹ,
Ti ko si s'oloogun ika?
Ṣe bi o sọ gbangba
Pe, bi mo ba sọ pe,
Ile wa ko n'iru wọn pe,
Irọ nla ni mo npa?
Tabi, bẹẹ kọ, ọmọ Ajiṣegiri?

Adeyẹmọ Ọjẹrinde

Bẹẹ ni mo wi,
Ng ko ni i yi ohun pada.
Ṣugbọn.........

Lawuyi Ogunniran

Ajao; Dakẹ! Yara mu suuru.
Ma ti i sọrọ rara,
Yara gbohun ẹnu mi,
Ajao Alayọ, ọmọ Irioṣẹjẹ.
Ṣe o sa mọ pe,
Onikangun l'o ni ikangun?
O si mọ pe, lai ṣawawi,
Alaisan l'o kangun s'ọrun?
Nigba ti o ti mọ pe,
Ko si idile t'o le fọwọsọiya
Pe, ile wọn ko l'oṣo,
Pe, ile wọn ko l'ajẹ
Pe, ile won ko l'eeyan ibi,
Njẹ nigba ti o mọ pe,
Bayi l'o ri kari aiye,
Kini ṣe ti o kuku gbiyanju
Ki o tọ arugbo inu iran rẹ lọ,
Ki o lọ beere bi
Oṣo oun ajẹ wa?

Adeyẹmọ Ọjẹrinde

Mo ti r'ibi ti o gọ si, ọmọ Ejigbọjọ,
Arun ti nṣe ọ l'ori ọrọ yi ni
Mo ti mọ delẹ.
Ekinni: Nṣe l'o rọra ndọgbọn
Ti o fẹ bu mi deledele;
O si fẹ d'ọgbọn kọ
Lati da mi lohun ibeere.
Kaka ki o jẹwọ pe,
Ẹru ajẹ nba ọ,
Tabi ki o kuku so
Nipa iṣẹ oṣo ṣiṣe,
O wa bẹrẹ si i dọgbọn,
O fẹ yi gbogbo rẹ s'ija.
Ṣugbọn, atiṣe mọ iwa enia l'o ṣoro;
Mo ti mọ ọgbọn t'o nda,
Mo ti r'ibi o gọ si gbogbo
Ng ko si ni i ba ọ fa a delẹ delẹ.
Bi o ba kọ t'oo sọrọ
Mo ti gbogbo rẹ s'ọrun rẹ
Iwọ Ayinde onitan, ọmọ ọdọ agba.

Lawuyi Ogunniran

O tan ng bi ko tan, ọmọ Ajiṣegiri?
Oko igbo l'a ni ki o ṣan,
Oko ọdan l'o gba!
Ope eniyan lasan
Ti npe 'ra rẹ l'amoye;
Bi ki i ba ṣe tori onkawe
Ng ki ba ti fun ọ l'esi ibeere.
Mo fẹ ki o ye ọ pe,
Ajẹ nbẹ ninu aiye
Bi omi ẹlẹgbẹ;
Ajẹ pọ bi erupẹ ninu duniyan;
Oloogun ika ko kere
Gbogbo wọn pọ kaakiri;
Olukuluku eniyan wọnyi
L'o nṣiṣẹ tirẹ ninu ika.
Nitorina, ọmọ Ajiṣegiri:
Bi o ko ba mọ tẹlẹ ri
Mo fẹ ki o mọ, ko si daju
Pe, oṣo nbẹ, ajẹ nbẹ,
Oloogun ika papọju
N'ile duniyan.
Idahun ọrọ ti o bi mi ree
Ṣugbọn mo fẹ ki o tẹti bẹlẹjẹ
Ki o tun gb'ọrọ miran:
Mo gbọ ti o tun sọ
Pe, ẹru oṣo nba mi,
O ni, ẹru ajẹ nba mi
Ati ẹru oloogun ibi,
O ni ẹru wọn l'o nba mi
Ti ko jẹ ki ng le sọrọ.
Mo fẹ ki o ye ọ pe,
Ẹru oṣo ko le ba mi rara
Nitori, mo gbẹkẹle Ọlọrun;
Ẹru ajẹ ko le ba mi
Nitori, mo gbẹkẹle Edumare;
B'o ti wu k'Oloogun ika gboju to,
B'Ọlọun fẹ, ko ni i le ṣe 'ru wa n'ibi
B'ẹẹ ni, awọn emere
Ko ni i r'ile mi ya.
Alaye ọrọ na ree o, ko ju bẹẹ lọ;
Ohun ti o bi mi ree, baba Kafilatu
Bi o ba wa l'alaye ọrọ;
B'o ba d'ijọ mẹjọ
Ki o jẹ k'a rira
Nitori aaye ko si l'oni mọ
G tun d'Ipade t'o nbọ.


## Tiger Tip

12
22
39

## Special Gift

4 8 35

Nap: 13 27 39 40



IWE IGBAẸLODE

DARA PUPỌ, RA TIRẸ NIBẸ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba ₦10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (₦1)
5 Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaṣoro (₦1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦6); Kekere (50k)
9. Iwe ala ni nla (₦2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi, Iṣin St Isalẹ Koto P. O. Box 17, Ilọrin

# Ẹgbẹ Birikila yan Oloye

NI aipẹ yi ni Ẹgbẹ Birikila ti njẹ Iranlowo Oluwa Ogbomọṣọ & District Bricklayers Company" yan awọn oloye fun ẹgbẹ won fun odun yi ninu ipade kan ti o waiye ni adugbo Akata nilu Ogbomọṣọ.

Awon Oloye ẹgbẹ na ni: Amuda Ajayi gẹgẹ bi Alaga; J. Ayinde igbakeji rẹ, J. O. Alabi Akapo ẹgbẹ; Emmanuel Oyebamiji akowe ẹgbẹ.

Ninu oro ṣoki ti o so lẹhin yiyan awon Oloye ẹgbẹ na, Ọgbẹni Amuda Ajayi dupẹ pupo lowo gbogbo awon omo ẹgbẹ na fun iru ayẹsi ati anfani ti nwon fun awon lati di opo ẹgbe na mu.

Ọgbẹni Ajayi jẹjẹ ni oruko Oloye yoku pe awon yio ṣe olotitọ ati olododo si ẹgbẹ na awon yio si maa wa ire ati ilosiwaju ẹgbẹ na ni ọnakona ati ni igba kugba.

Ọgbẹni Ajayi wa ro awon omo ẹgbẹ na lati gbaruku ti awon ki ete ati ero ẹgbẹ na le yori si rere.

# Abajade Idanwo Bibeli

IWỌNYI ni orukọ awọn enia ti o ṣe daradara ninu Idanwo Bibeli ti o jade ninu Imọlẹ Owurọ 16:4:77:

MARAARUN

Awọn enia ti o gba maraarun ni: Sunday Ọnaniyi lati Ogbomọṣọ, Layiwọla Ayinde lati Ibadan, Joseph Ọlajide lati Eko, Sunday John lati Ogbomọṣọ, Oluṣọla Adeagbo lati Muṣin, Oluwọle Oketọla lati Ogbomọṣọ, Taiwo Ṣoye lati Eko, Layiwọla Oyewọ lati Ogbomọṣọ;

Nathaniel Abiọdun lati Ado-Odo, S.A. Abidogun lati Ogbomọṣọ, James Otukpe lati Apapa, R. A. Ayanwale lati Ogbomọṣọ, S. O. Oguntolu lati Ilero, J.A. Ṣangotọpẹ lati Ogbomọṣọ:

James Ibidọja lati Arandun Kwara, Josiah Korede lati Ogbomọṣọ, Florence Ọdẹrinde lati Ikẹja, Srmuel Afọlabi lati Ogbomọṣọ, Sunday Akanbi lati Oṣodi, Toyin Ọlapade lati Ogbomọṣọ ati Job Oyelakin lati Ṣomolu.

MẸRINMẸRIN

Awọn enia ti o gba mẹrinmẹrin ni Ṣẹrifatu Busari lati Ibadan ati Aarinọla Amọpe lati Ibadan.

IDAHUN IBEERE

Iwọnyi ni itọkasi idahun awọn ibeere na:

1. 1 Tẹssalonika Ori 4 ẹsẹ 16
2. 1 Tẹssalonika Ori 5 ẹsẹ 2
3. 1 Tẹssalonika Ori 3 ẹsẹ 10
4. 1 Tẹssalonika Ori 5 ẹsẹ 11
5. 1 Tessalonika Ori 5 ẹsẹ 21.

Ẹ tete fi idahun nyin ranṣẹ si Onidanwo Bibeli ni Adirẹsi isalẹ yi.

FUN TITA

A ni Iwe "Ibeere ati Idahun Inu Bibeli" fun tita. Fi Naira kan ranṣẹ si:

Apostle K. Kobiowu,
(Onidanwo Bibeli)
S2/81 Oranyan St.
Ibadan.

## Lati owo Karimu Kobiowu

# Alufaa Dauda fomoyo

NI ọjọ karun oṣu karun ọdun yi ni Alfa Dauda Akanni ti agbo ile Bangọ nilu Ogbomọṣọ fi ọmọ rẹ obinrin, Arabirin Afusatu Akanni fun Ọgbẹni Saka Yesuf ti agbo ile Ofeegun nilu Ogbomọṣọ ni aya. Iṣẹ Alafaa ni Dauda Akanni nṣe, ọmọ rẹ si jẹ oniṣowo nilu Ogbomọṣọ; bẹẹ si ni Saka Yesuf na jẹ oniṣowo pataki nilu Jos l'Oke-Ọya.

Alhaji Jimọ Biboaṣiri l'o ṣaju eto akanṣe adura nibi ayẹyẹ siso-yigi tọkọtaya na ki inawo to wa bẹrẹ ni ọjọ keji.

Ọpọlọpọ awọn Alhaji, Alhaja, Alfa nlanla ati awọn gbajumọ ilu pẹlu awọn orekelẹwa obinrin l'o pẹju pesẹ lati ba wọn ṣe ayẹyẹ siso yigi na. Inawo ọjọ na kọyọyọ.

Die ti aaye wa fun lati darukọ l'ara awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni Oloye P O Ogunniyi, Ọgbeni M. A Ọlọrunvọmi, Oloye Alasa Lafimi, Oloye Buraimọ Ayandeji, Oloye Abesẹ Odutọna, Oloye Olugbọn, Oloye Arolu; Oloye Belo Alamu Akintaro II ti iṣe Baalẹ Iṣegun Ogbomọṣọ ati agbegbe rẹ; Alfa Ayangbami ẹgbẹ Anabidun, Jacob Akinlọtan, Bayọ Alata, Alhaji Yesuf Alao.

# Odun Eegun Ikirun pari

NWỌN ti pari odun egungun ati ti ogun nilu Ikirun gẹgẹ bi irohin ti o tẹ wa lowo ti wi. Odidi ojo meje gbako ni nwon fi ṣe odun na.

Ni akoko na, awon egungun ati Ologun na ṣetutu fun alaafia ati ilọsiwaju ilu Ikirun, ti Ipinlẹ Ọyo ati ti Naijiria lapapọ.

Lẹhin eyi ni nwon lo ki Akirun ni aafin rẹ.

Ninu oro rẹ fun awon olodun na, Ọba Adeyẹmi Oyejola Keji yi nwon fun ṣiṣe odun na ni iroworosẹ.

Ara awon enia ti o nipa ninu odun na ni: Oloye Gbadamoṣi Ọyawu ti iṣe Oluodẹ Agba, Eesadẹ Ogundajo Ogunmola, Oloye Salami Ggunniyi ti iṣe Oluode Fekẹtẹ ati Babaodẹ Isalẹ Ikirun. Oloye Ṣangoranti Raimi Amoo.


## Wanted

APPRENTICES and advanced apprentices are wanted in our Printing Section.

Remuneration is very attractive. Bring your application by hand to the Manager:

NIGERIA NEW STATES CO;
18, Ọdunlami Street,
Lagos.



## Yasin ati Isawaka

EYI ni lati kede fun ẹnyin onibara wa ti ẹ ti nkowe si wa lati ọjọ pipẹ pe, a ti ni Yaasin ati Isawaka ni ede Yoruba ati Wutuba rẹ.

Adura pataki ni fun Musulumi. 50k ni Ẹyọkan, N2. ni Dosinni rẹ.

Tete fi owo ranṣẹ si:-

Alufaa Igbaẹlode
N2/394A Odoiye
Adeoyo Rd,
P. O. Box 3365
Mapo, Ibadan

(2) Alufaa Igbaẹlode
Moṣalaṣi Idi Iṣin St;
Iṣale Koto,
P. O. Box 17
Ilorin


# Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

12,479 Mudaṣiru Iṣola, Iwo.
12,480 Ayodeji Ajayi, Ileṣa.
12,481 Mudaṣiru Okunola, Ifẹ.
12,482 E. O. Brahima Eko.
12,483 Lasisi Alowonle, Ọyo.
12,484 Dauda T Yusuf Onijo Kwara
12,485 Aṣimiyu Ọlapade, Ibadan
12,486 Sunday Samuel Ileṣa
12,487 Tunde Idowu Fegge-Onitsha.
12,488 Ramoni Sheriff, Ilorin
12,489 Raimi Owolabi Siẹ
12,490 Sunday Ọladeni Iseyin
12,491 J. Okunọla Ogunkanmi, Ode-Omu
12,492 Raimi B. Alabi Agbado
12,493 Oluṣola Ayorinde Abẹokuta
12,494 Florence Babafemi, Imẹsi-Ile
12,495 Pinpinlade Idowu, Ibadan
12,496 Abiodun O Ọladẹjo, Ogbomọṣọ
12,497 Akintunde Famodimu, Igbajo
12,498 Sikiru Kọlapo, Apomu
12,499 Adegboyega Akerele Ila-Ọrangun

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA DI

## Omo gbe mole Owuro

Iwe Idi Ọmo Ẹgbẹ)

Oruko rẹ.....................................................

Adirẹsi rẹ.....................................................

Ọmọ Ilu ti o jẹ.....................................................

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akowe Ẹgbẹ)
P.M.B. 5230, Ibadan.

# Agbéyẹ̀wò ohun titun t'o gbode

REKỌDU, IWE, ORIN, ARE-IDARAYA.

# Awo Layigbade gbayi

LATI ỌWỌ BỌLAJI BABALỌLA

Awo titun kan ti gbajumọ alare Sakara nni nilu Eko, Saka Ọlayigbade ṣẹṣẹ ṣe jade, eyi ti o pe ni "SYSTEM 5" ti di ohun ti gbogbo enia ni Ipinlẹ Eko, awọn alafẹ enia fi nṣe orin kọ bayi.

Awo na ti Ile-Iṣẹ aṣe-awo ADETUNJI OMOAJE SOUND STUDIO gbe jade ni ipari oṣu t'o kọja gbayi, o si ti gbẹyẹ kaakiri gbogbo ibiti nwọn ba nṣe inawo bi ikomọjade, igbeyawo, isinku, iṣile ati bẹẹbẹ lọ.

O tilẹ ṣele pe ẹrọ-ikọrin (Amplifier) ni wọn lo nibikan, rẹkọọdu Saka Layigbade (System 5) ni awọn enia na sa nbeere fun titi nwọn fi tuka.

Ninu awo na ti nọnba rẹ jẹ 01PS 0121 ni Saka Layigbade ti ta Goje Aramọnda rẹ pẹlu Orin atata ati ilu Sakara agbọdunnu ti Ijinlẹ Owe Yoruba ti o ba orin ti o nkọ mu si njade lati ọwọ Oniyalu rẹ.

Ni oju kini awo yi, Layigbade bẹrẹ pẹlu orin ti o kọ ni iranti Alhaji Latifu Ayinde Owokoniran ti o jẹ gbajumọ enia nigba aiye rẹ ti o ku si ilẹ mimọ Meka ni asiko irinajo Mimọ ti o ṣe l'ẹdun t'o kọja si ilẹ na.

Nibẹ ni o ti ran gbogbo wa leti nipa iku. O ni, o ki baa jẹ Olowo tabi talaka, ọmọde l'o jẹ ni tabi agbalagba, ki a ranti pe, iku ojiji ni yio de ba enikọọkan wa gẹgẹbi ti ọdọmọde Haji Owokoniran ti o lọ lai dagbere.

Nitorina ki a maa huwa rere nitori ti a ba lọ, ki araiye le rohin wa si daadaa.

Gẹgẹbi awọn Agba ti wi pe, adura ati saraa ni ounjẹ oku. Saka Layigbade wa bẹrẹ si i ṣe akanṣe adura fun Oloogbe Alhaji Owokoniran o si tun gbadura pe ki Ọlọrun tu awọn obi rẹ ninu.

Nipa ki a ki enia ki ori eni wu pẹlu oriki idile ti a fi bi ni, Saka Layigbade lo ni iyẹn Ninu awo yi, awọn enia ti o ki sibẹ ni o ki ni ọna ti o wu ni lori. Awọn ni Raimi Ọladipupọ Jinadu, Mọṣudi Anifowoṣe.

L'odi keji awo na, ọrọ atata ti o yẹ ki enia maa so nigbagbogbo ni o fi bẹrẹ rẹ. O ni "Pẹki mo ko ire". Tabi taa ni ko fẹ ki oun ko're? Lẹhinna ni o wa soro nipa Iya eni. O ni oriṣa bi iya ko si.

L'oju yi kanna ni o tun ti ki awọn Ejirẹ Eyila eyi ti mo si lero pe gbogbo ẹni ti o ba jẹ ibeji tabi bi ibeji ni o yẹ ki o ni awo na nile nitoripe Saka ki wọn dọba nibẹ.

Ki a mu ti ẹgan kuro, Saka Layigbade ronu jinlẹ ki o to ṣe awo rẹ Are faaji na fakiki, gbogbo enia l'o si nsọ pe "Abibu Oluwa mirann ni o tun yọju fun awon" ni, Eko ati pea aye oloo gbe Abibu Oluwa ti o si silẹ lati ọdun pipẹ wa lai si alare ti yio di ni Saka ti di.

Awo rẹ na ti wa kaakiri gbogbo ile itaja rẹkọọdu jakejado Naijiria tabi lọdọ.

Adetunji Records Stores
2, Ibomo St,
Agarawu, Eko
Tel. 26813.



SAKA LAYIGBADE
Onisakara Atata

# Ofin titun jade lori Adigunjale

IJỌBA Ologun Apapọ ti tun ofin Adigunjale ilẹ Naijiria ṣe.

Nipa atunṣe ofin na, ko si aaye fun ẹnikẹni ti ile ẹjọ adigunjale ba dalẹbi iku lati pẹjọ kotẹmilọrun si ile ẹjọ gigajulọ ilẹ Naijiria.

Ninu ofin na ti Ijọba Ologun Apapọ gbejade nilu Eko ni ipari ọsẹ ti o kọja, ofin na sọ pe bi ile ẹjọ adigunjele kan ba da ẹnikan lẹbi ẹsun idigunjale ko gbọdọ ju oṣu kan lo ti iwe bi nwon ṣe ṣejo na gbodo fi de odo Gomina Ipinlẹ ibi ti iru ẹjo bẹẹ ba ti waiye.

Ẹwẹ, ofin na so pe ko gbodo ju oṣu kan lo ti Gomina kan ba ti gba iwe eto ẹjo idigunjale kan, ti iru Gomina na gbodo fi fi owo si tabi lati ma fi owo si iru idalẹbi bẹẹ gẹgẹ bi ofin ti gba a l'aye lati ṣe.

Ijoba so pe lati ojo kokanla oṣu karun odun yi ni ofin na ti bẹrẹ ni jilo, oun ni o si bori atunṣe ti odun 1974 ti o gba ẹni ti ile ẹjo adigunjale ba dalẹbi lati pẹjo kotẹmilorun sile ẹjo gigajulo ilẹ Naijiria.

Nitorina lati igba yi lo, ẹnikẹni ti ile ẹjo adigunjale ba dalẹbi iku, ti Gomina na ba si fowo si i, kiakia ni nwon yio maa pa a.



ỌGAGUN OLUṢEGUN OBASANJỌ
Olori Ijọba Naijiria

# 32 & 47

# Awon Onifa-yawo yio maa f'ara gb'ota

IJỌBA Ologun Apapọ ti yari patapata bayi tori iwa fayawọ ni ilẹ Naijiria, nwọn si nfẹ mu iwa na de opin ni gbogbo ọna.

Nitorina, Ijọba gbe ofin ologun kan jade pe, lati oni lọ, onifayawọ ti o ba pa onisẹ bode lara pipa ni a o pa a

Bakanna, Ofin na sọ pe, onifayawọ ti ọwọ ba tẹ, ẹwọn ọdun marun ni o nlọ, ko nii si pe ile ejọ ngba owo itanran lọwọ wọn mọ.

Siwaju si i, ofin na sọ pe, ẹru fayawọ yowu ti nwọn ba ri gba lọwọ awọn onifayawọ, a ko ni i ta a fun ẹnikẹni mọ ina ni a o maa da sun un l'oju awọn ọga lati ile isẹ Ologun; ti Ọlọpa ati ti onibode.

Ijọba Apapọ sọ pe, ohun ti o mu ki ofin na waiye ni orisirisi irohin ti o nkan Ijọba pe, iwa fayawọ ngogo si i ni ilẹ wa tobẹẹ ti awon onifayawọ tilẹ ndira ogun kọlu awọn osisẹ onibode pelu fun ijọba Apapọ, Ọgagun J. J. Olulẹyẹ tisalaye lori ofin titun na. Ninu ọrọ rẹ ti o sọ fun awọn Ọgalọga nile isẹ onibode nilu Eko ninu ọsẹ yi, Ọgagun Olu lẹyẹ sọ pe nitori ki iwa fayawọ le d'opin ati nitori ki ewu ma baa wu awọn osisẹ onibode mọ ni awọn se se ofin na.

OLULẸYẸ SỌRỌ
Alakoso Eto Isunna

Ọgagun Olulẹyẹ rọ wọn lati fọwọsowọpọ ninu aniyan Ijọba lati gbogunti iwa fayawọ "nitori bi awọn osisẹ onibode ko ba ba awọn onifayawọ mulẹ, kiakia ni Ijọba yio sẹgun iwa fayawọ ni ilẹ wa".

Siwaju si i, Ọgagun Olulẹyẹ sọ pe, ẹsun nde si eti Ijọba nigbagbogbo nipa iwa awọn ologun kan paapaa ni papa ọkọ ofurufu ni Ikẹja pe, nwọn nfi ẹhin pọn awọn onifayawọ.

O wa kilọ pe, ki ologun yowu ti o ba nlo ipo rẹ lati ru ofin lọ mọ pe bi ọwọ ba tẹ wọn, oju wọn yio ri mọbo nitori ki enia jẹ ologun ko sọ pe ki o ma pa ofin mọ.

# Ofin jade lori tita epo moto

IJOBA Ologun Apapọ ilẹ Naijiria ti gbe ofin titun jade l'ori tita epo mọto ati iru epo miran ti a nwa ninu ilẹ.

Ofin na sọ pe, Ijọba ti fagile gbogbo iwe asẹ ti a ti fun awọn ti o nta epo mọto tẹlẹ.

Ofin na sọ pe lati igba yi lọ, ẹnikẹni ti yio ba ta epo mọto ati iru epo yoku ti a wi na, o gbọdọ gba iwe asẹ nibi ile isẹ akoso eto epo inu ilẹ ati ti ina.

Ofin na sọ pe, ẹnikẹni ti o ba nta epo ti a wi yi lai gba iwe asẹ, ẹwọn ọdun meji ni yio lọ tabi ki o fi ẹgbaa Naira (₦2,000 00) tanran tabi ki o sanwo tanran tan ki o tun fi ẹwọn jura.

Siwaju si i, ofin na sọ pe ẹnikẹni le ta epo karosinni ti ko ba ju ẹẹdẹgbẹta galọọnu (5̣0 litres) lọ lai gba asẹ.

Amoye kan fi ye wa pe ohun ti o mu ki ofin yi waiye ni iwa awọn onisowo epo buburu kan ti nwọn nfi iwa mọkaruru wọn mu ki epo wọn ninu ilu.

O ni iru awọn enia ti a nwi yi ni o maa nlọ rọ epo mọto sinu gorodoomu nlanla, ti nwọn maa nlọ gbe e pamo sinu igbo tabi sinu ile, ti nwọn si nta a ni owo gege fun awọn ara ilu. Nw n ni awọn gan-an l'o nfa a ti epo mọto fi i wọn l'ọpọ igba.

**Sulu 7 12 26**

**Tip 9 12 14 27 35**


OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

**WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD**

TI TUN GBE ERỌ ARAMỌNDA KAN DE.
ẸRỌ NA NI A NPE NI



**Solo Lawn Mower (N266.00)**

(EYI NI ẸRỌ TI A FI NGEKO)

Meji iru ẹrọ yi ko si rara
Ni ilẹ Naijiria.
Bi oko ti le wu
Ki o kun tabi pọ to
Ko jẹ nkankan l'oju ẹrọ na,
Ni kiakia ni yio pari rẹ.
Iwọ ti o ni ọgba l'ayika ile rẹ,
Ati ẹnyin alasẹ ile iwe,
Ẹrọ yi ni ki ẹ maa lo.
O dun i geko pupọ,
O si ni alopẹ.
Owo ẹrọ na ko pọ rara
₦266.00 pere ni.
Tete wa ra tirẹ ni:

**Western Nigerian Technical Company Limited**

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.


Printed and published by the People's Star Press Limited, N4/496B Yemetu Aladorin P. M. B. 5230, Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran, E4/803, Aperin Adekile Ibadan. Lagos Office 18, Odunlami St, Phone 27017.